E ma ka Irohin Imole Ni Igba Gbogbo

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofo ti -:
ANOYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KETA
LATI OWO
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. 1 No. 52 WEDNESDAY JUNE 25, — JULY 1 1958 KỌBỌ KAN (1d)

# Enmo de! Obinrin kan tun po "Eiye aje" lenu

**NI NKAN BI AGOGO MỌKANLA KU IṢẸJU MẸDOGUN ARỌ NI ỌJỌ KEJI ỌSẸ TI IṢE 2/6/58 NI OBINRIN KAN TI A NPE NI ADETOUN ỌMỌ ABẸOKUTA PỌ ẸIYẸ AJẸ NINU ṢỌỌSI APOSTOLIC CHURCH NI 6, IYASUNA STREET, IDI — ORO NIGBATI EVANGELIST AGBỌNA NGBADURA FUN.**

Okiki tun kan gbun un, pe obinrin miran tun pọ ẹiyẹ ajẹ lẹnu lẹhin ti akọkọ ti o pọ ẹiyẹ ajẹ ninu Ṣọọṣi kanna yi, Ọgbẹni J. O. Shoyinka aṣoju wa ni Mushin ni ọrọ yi ṣẹlẹ loju rẹ gan, ohun ti o si mu lọ sibẹ nipe nigbati iro kan lara pe Woli Agbọna tun la oju afọju, o fẹ lọ wadi bi irọ ni, bi otitọ ni ki o to ba obirin yi nibiti o ti nja rapa nilẹ ti o si pọ ẹiyẹ ajẹ yi. Ni kukuru awọn ibere wọnyi ni Ọgbẹni J. O. Shoyinka bere lọwọ rẹ.

Aṣoju— Kini orukọ rẹ?
Ẹlẹiyẹ— Adetoun
Aṣoju— Ọmọ ilu wo ni
Ẹlẹiyẹ— Ẹgba—Abẹokuta
Aṣojo— Kini gbe ọ dehin?
Ẹlẹiyẹ— Mo wa gbadura ni
Aṣoju— Tani ṣe okunfa rẹ de ihin.
Ẹlẹiyẹ— Ẹgbọn mi Victoria Oluwẹminiọ ni.
Aṣoju— Ilu wo li o ngbe?
Ẹlẹiyẹ— Ọmi leti Ibadan ni
Aṣoju— Kini ọjọ ori rẹ?
Ẹlẹiyẹ— Adọta ọdun.
Aṣoju— Nigbawo lo ti ṣakiyesi pe ẹiyẹ ajẹ wa lara rẹ?
Ẹlẹiyẹ— Ọdun kan.
Aṣoju— Bawo ni o ṣe mọ pe ẹiyẹ ajẹ ni?
Ẹlẹiyẹ— Ti mo ba sun ni oru, nkan na a ma ru gudugudu ninu mi, ni oru ganiọ, ọpọlọpọ ẹda ti o ti ori jọ obinrin, ṣugbọn wọn gunyẹ, won si ni agogo bi fi ẹiyẹ, a ma pagbo yi mi ka, won a si gbe ẹran tuti o nṣọjẹ bolobolo siwaju mi pe ki a jọ ma jẹ ẹ, a si jọ ma jẹ e. Nigbati ẹiyẹ bẹrẹsi yọ mi lẹnu ti mo si gbọ pe Woli kan wa ni Mushin ti o njeki pọ Eiyẹ ajẹ ni mo ṣe wa, mo si pọọ, Ogo ni fun Oluwa, Modupẹ lọwọ Woli Agbọna gidigi.

Enyin Olukawe Irohin Imolẹ, ma jẹki a gbọ, iro ni mu wa, enikẹni ti ọrọ yi ba fẹ ru loju pe boya irọ ni, le lọ ri Woli Agbọna, No 6 Iyasuna Suna Street, Idi-Oro. Woli yi ula oju Afọju, o si nse orisirisi Iwosan—Irohin ko to afojuba lọ foju ara rẹ rii.

Eiyẹ Ajẹ kini ati ekeji wa ninu Igo ni Ṣọọsi re ati Afọju ti o la loju.

## AWON IWE KOSEMANI TI O WA NILE FUN TITA NISISIYI

| | |
|---|---|
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun lede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bisiriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Iṣegun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Eyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranṣẹ si :-
Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Metta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

AWỌN IWE TI A ṢẸṢẸ FẸ TẸ JADE
Igbo Eṣubeleke (kikun) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako (kikun). 4/6d Ayunọrunbọ ati Panpalaṣo 4/6d, Ajiran Ilu Oku (kikun) 4/6, Ṣebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafary Sere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-
Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade

## Awolowo ni: Naijiria ko ni gba ase onikumo

IBADAN
NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori Egbẹ Afẹnifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinle Iwọ-Orun to kuro ni Ibadan nia a lọ si Apejọ awọn Alakoso Ijọba Naijiria eyiti Alhaji Tafawa Balewa pe won si ti o si ti ṣe alaye yi fun gbogbo awọn enia pe Naijiria ko ni aṣẹ onikumọ fun Ominira Apapọ Ijọba Naijiria.

O ni iṣu on dun lati ba awọn Alakoso Ijọba ẹlẹgbẹ on ṣe ipade ti awọn fẹ ṣe yi fun ipalọniọ orisirisi eto ti o yẹ fun ipalẹmọ Ominira Ijọba ti apapọ Ijọba ti Naijiria fẹ gba ni ọdun 1960. O ni iba dara papọ ti o ba ṣe le jẹ pe eto awọn yio papo lori ipade eto iṣelu na ti awọn nlọ ṣe ni ilu Oyinbo ninu oṣu kẹsan ọdun yi ti enu awọn ba le ko lari eto ti yio fun gbo ilu Naijiria ni idera.

O ni o ṣe on ni anu lati sọ pe ipade ikọkọ ti awọn alakoso Ijọba meji lọ ṣe pelu ara wọn ni aipẹ ti mu ifura ba gbogbo enia gẹgẹbi irohin ti a ngbọ lati okere pe lori ki wọn le ma fi aṣẹ onikumọ teri gbogbo awọn enia Naijiri a ba ni



ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

O ni awọn Ebgẹ Afẹnifẹre ti on jẹ Olori fun si ti sọ fun on ninu ipade wọn pe on ko gbọdọ ba enikẹni di imọlu pọ gba aṣẹ onikumo fun Apapọ Ijọba Naijiria lati ma fi tẹ ori igbogbo awọn ba, aṣẹ ki enia ma gbọdọ sọrọ si ọran iṣelu gẹgẹbi bi o ba ti ro pe o le dara, aṣẹ ki enia ma gbọdọ tọkasi i fun Egbẹ Ọṣelu ti Ijọba ba le wa ni ikawọ rẹ pe o tọ ki nwọn tọ ọna bayi afi eniti o ba kan ijọgbọn.

O ni iwọn iba ọna iṣẹjẹ ti Ijọba Gẹẹsi ti fi ẹsọ wa le yi to fun wa lati fi ṣe eto iṣelu Ijọba wa ti yio fi mu irọrun fun gbogbo ọlugbe Naijiria. O ni ona ti yio da aabo bo awọn ọlọla ati awọn taluka ti gbogbo mẹkunnu ilu yio fi ni alafia ati ifayabalẹ ni awọn jẹ ni ọwọ si ni ti awọn ti ko k ni si rogboyan.

# Omo Najiria E faramora

OJQ nde, ọjọ nlọ, ọdun de, ọdun nyipo, ọjọ iba jin bi ọna efẹ bo pẹ titi a wọle. Bi iṣẹju gun gun gun a di wakati, b'ọjọ pọ titi a d'ọdun, bo pẹ titi ọdun 1960 a de, gbogbo wa a gb'ominira.

Ṣugbọn kojọ yi to de, ẹ jẹ ka yẹ ara wa wo, ẹ jẹ ka ṣe 'dokita' ara wa, ọmọ enia dudu, ẹ jẹ ka fi awọn ero iṣiwaju kọgbọn, ki ominira ma ba di omi inira fun dede wa, ẹ jẹ ka fara wa mọra, ka sowọ pọ lati ibẹrẹ, nitori ọwọ kan ko gbe ẹru dori.

Bi igi igbo parapọ nwọn a di igbẹ, bi odo kekeke pawọpọ nwọn a di okun, bi Naijiria ba parapọ, nwọn a d'alagbara. Atẹwọ lara igunpa niyekan, k'Ibo mọ Yoruba ni ọmọ iya, ki Hausa mọ Ibo ni iyekan ki Yoruba ma ya ọkan sọtọ rara, k'aiye ba roju fun dede wa.

Ọmọ Naijiria nsaisan, aini isowọpọ ni arun wọn, ohun fa aisan yi ko ṣi soro ri, se irira ni nle lọtun losi kiri, ngo wi nko ni saisọ, nitori a ki tori gbigbo paja o daju, a ki tori kikan pagbo, eruwọ, bẹni a ki tori bekebeke 'p'obukọ, mo juba Olodumare, awo ajiki mo juba Olodumare, awo ajipe, igi lehin ogba aṣe otitọ. Olugbala oninu re.

Iba Adio eki ọmọ Kẹsinro, Afinutan ni ma tan ni jẹ, Ekun baba Afọlabi. Mo ti juba baba ọrun, mo juba okun fa mi saiye, mo juba dudu, mo fi iba fun funfun iba kekere, iba agba. Nitori mo fẹ sọ otitọ kikoro, ki ẹ sọ mi di ewe ẹkọ dandan, nitori bi ọmọde j'ekọ a dariji ewe, o daju Mo fẹ sọ otitọ, ẹ jẹ nwi nko ni saisọ, bi agba ba jẹ igbin a dariji ikarawun ngo wi, nko ni saisọ.

Arun to yẹ ki a wosan kojọ nla to de, e jẹ nwi ẹ ma dimi lenu. Qga Basi, ko fi ika kan ja ẹsẹ nitori ati sẹgun. Ọkunrin nla aṣoroko bi a ko ba jeun kanu, O pa ika marun pọ, lo fi ndolori gbogbo wọn.

Ọmọ Naijiria, ẹ sowọpọ ẹ dọkan, ọmọ enia dudu ẹ parapọ, e ye tuka, ẹ jẹ ka fun ara wa lọwọ, ka mọ eruwọ ara wa. Edumare ma jẹ ki ipọnju wọ'lu pẹlu ominira, Qba oke ma jẹ ka jin si koto igbekun. Ọtun wẹ osi, osi wẹ ọtun ni dede ọwọ fi mọ. E jẹ ka pawopọ fun ilọsiwaju gbogbo wa

Emi nkigbe 'iṣowọpọ iṣowọpọ' ti ko fi hu iwa o ye ki a mọ pe ọta alafia on igbadun ni ise. Ọmọ Naijiria, ẹ ma diju sọrọ Faranse, ẹ ma diti si ọrọ wọn. Iba se pe ẹgbẹ oṣeln Faranse papọ soju kan ni Inira ko ba pọ fun ilu Ol'ominira, iba se pe nwọn fa ara wọn mọra ni, katakata ko ba gbilẹ bi ogẹdẹ ẹ jẹ ki a fi eyi kọgbọn ki eni jin si koto kọ awa toku lọgbọn, ki dede wa di ọlọgbọn laiye wa, aifaramọra a sọ wa dọta nigbehin, aisowọpọ a sọ wa dole loju aiye lẹhin ominira.

Lati Qwọ:—
AFQLABI QLABIMTAN

---

Ọpọ ope ni o ntori asiwọju wọn ja ija ilu, ọpọ omugọ ni o ntori olori ẹgbẹ wọn fa ọbẹ yọ, bẹ Asikiwe ti re Kaduna, o gba Sadauna lọwọ Awolọwọ t'on Asikiwe ki se ọta ara wọn Opo igba ni tọtun tosi ti pade nidi are, aimọye igba ni nwọn ti rẹrin si ara wọn Eto iṣelu ki ise ọrọ ija rara, Ile iṣelu ki ise oju ija ogun at'Asiki at'Awo ni o nwa ilọsiwaju ilu, ona kan ti ko wọ oja ni o nfa iyonu, otun a ro pe ona tosi ko ya osi a ro pe ona totun ko dara, ariyanjiyan a si de nitori ati salaiye fun gbogbo wa.

Ṣugbọn ope a so ariyanjiyan yi dogun, alaimokan a so ariyanjiyan yi dotẹ, se opo ẹda ni o nrijẹ ninu iwa buruku, ogoro omo adamo ni o nrijẹ ninu ija igboro nwon a fi ẹte sile pa lapalapa nitori ati yi alaimokan siwa buruku, nwon a yogi si isowopo Naijiria loju gbogbo wa, mo ke-ke-ke nko ri ẹni ke si, mo fọ fọ fọ nko ri ẹni gbo temi.

Ṣe o ni iwọn mo gbodo sọ nitori ati gbowo ẹ ba oga ni nko gbodo lanu tan nitori iṣẹ, nwon ni nko gbodo soro ju nitori owo osu, bẹ bi o ba ṣe bi iṣẹ mi ni, nba lu ilu yi iba dun, dun, dun, nba soro yi iba kun gidigidi, ṣugbọn nko ro oko, bẹni nko yẹ ona, gege ni mo fi njẹun, ẹ sa nle ọmọ isalẹ ni oke, ẹ ni ẹ nwa isowopo, ẹ ngbin igi otẹ kakiri ilu ẹ ni ẹ nwa ilosiwaju wa, ogoro tori ati di oṣelu dota omo iya, omo iya mẹta tori owo ndi oselu nilẹ wa.

Ọpo ntori ifẹ owo njija ibo, ṣe opolopo alainifẹ ilu lo ti d'oselu nitori ati gbowo wa, opo oselu ni o nlo ida fun iyekan, ṣe ẹni ko pa ogorun poun l'odun ẹbora ani o npa igba, owo ori a so ẹni ko dibo fun wọn d'onigbese, owo onipo a le eni ko fe tiwon kuro ni ilu, a gbe ẹni fe tiwon safefe rere, Ileto ti ko dibo febora a rehin f'odun marun, gbogbo anfani a jinna si won, be asiwaju nama ni o nfa nama wogbe.

Nigbati aṣiwaju ba nya si oto, kini ki mekunu yio se? Iba ṣe pe oṣelu ngbagbe eni ko dibo fun won ki nwon ka totun tosi si okan, ki nwon ranti pe owo tomode tagba lawon nna bawo ni irepo ba se ma po to, bawo ni igbadun iba se ma to fun gbogbo wa, emi iba je oselu ntemi, mba fi gbogbo ara ṣiṣẹ tititi, mba fa otun pelu osi po, mba so gbogbo Naijiria dọkan, mba dojuti awon eni so pe nko ni ṣaiye 're.

---

## IYA NI WURA, BABA NI DIGI

O bẹrẹ lati oju ewe keji leje ki e gboro enu mi Bi e ba di ọlola bi e di olola, e se iranti wipe iya ni wura, baba ni digi, ogoro enia lo wa ni ode aiye toni, ti nwon ti di afore su nise, Iya a ri won pose, Baba a ri wọn banuje.

Ki isi ṣe ntori airije, tabi airimu awon omo nwon ni- Oti o, awon omo wonyi ni owo lowo bi sekere, omo nbe lowo won bi ogedẹ, ẹru nbe ni ẹhinkule, iyawo mbe lodedẹ.

Ṣugbon, A! iwo orẹ mi iya to bi nwon ko se fi oju ri, Baba won ti di baba yi.

KO TI PARI


# EMPIRE *Aristocrat*

The Stationery Stores hereby announce that they have been appointed the Sole Agents of The "EMPIRE ARISTOCRAT" Portable TYPEWRITERS



The "EMPIRE ARISTOCRAT" Portable Typewriters manufactured by the British Typewriters Ltd. of Bromwich, LONDON.

A REALLY MODERN PORTABLE TYPEWRITER FOR EVERYONE WITH WRITING TO DO...

GUARANTEED FOR ONE YEAR — WEIGHS ONLY 9. LBS. PRICE £21

Leaflets, Sales and Service :-

The Nigerian Office Stationery Supply Stores

196, Broad Street, P. O. Box 148, Phone 22530 & 20973, LAGOS

57, Oniroke Street, Phone 480, IBADAN.

